**Asoje**

Ala ti eje ba la inu wa lo ngbe enikan ko mehun ela. E yeke se eke lo npani, gudu gudu bọinbọin ẹni to ba wu ki o bẹ.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

**Owe**

Aṣẹṣẹ ko ni... Owe ... Atẹ ... Aiye ko ... ko ... ko da ...

VOL. XII No 689 LAGOS. SATURDAY AUGUST 20, — AUGUST 26. 1960. KỌBỌ MEJI (2D)

# Pagidari Igida ! Odo Ogunpa Kun Akunya Nilu Ibadan

Aramẹriri ni ẹkun'mi odo Ogunpa ti ọdunni nilu Ibadan, jamba ti o ṣe ko lẹgbẹ. Ọdọdun ni omi yi ma nkun ṣugbọn ti ọdunni pa bambari.

Ogunpa jẹ odo agbara kan ti ima ṣan lati ọna Ẹlẹiyẹle kọja gba arin Eko tedo, on kanna lo kọja ni Ọja Dugbẹ lọ si Gbagi titi lọ gba Oke-Ado lọ si ọja Ibukọ.

Ti o ba di igba ojo, ama kun akunya ni Oke Bọla tobẹ ti awọn ara Oke-ado ko fi ni le wọ ọ sọda si Isalẹ Osi.

Ni ọdun kan, niwọn ogun ọdun sẹhin ni omi odo Ogunpa yi kun tobẹ gẹ ti o fi wọ ṣọṣi Ogunpa, o si gbe ile miran lọ ni isalẹ Ekotẹdo ati ni Oke-padi.

Ṣugbọn a gbọ laipe yi wipe odo Ogunpa yi kun akunya lodun ni, ọpọlọpọ ile lo si gbe lọ gbogbo awon ti ipatẹ won mbẹ leti odo yi, gbogbo ọja ti awon fi patẹ ni odo na ko lọ.

Ọkunrin gbajumo kan ti o gbe moto rẹ silẹ ni eti odo na wọle lọ ki ọrẹ rẹ, ki o to jade kuro nibẹ ni ojo nla kan rọ, o si di agbara ti o ya lu Ogunpa o si kun bo moto na molẹ tobẹ ti o jẹ wipe agbara kaka ni awon fi wọ moto na kuro ninu omi odo Ogunpa.

Paripari rẹ o gbe ọmọ ilewe Onlwe marun kan lọ pẹlu.

## T'OKO T'AYA KU LOJU KANNA

ABẸOKUTA—Obun iyanu lo ṣẹ fun gbogbo ena l'ti gbọ ti iku baba wa Oloye Isaac Oyedoku Ṣorunsen ti o ngbe Agọ-Oko ni gbaro ilu Abẹokuta, ni ọjọ Wednesday 10th oṣu August, 1960, ni agogo mẹrin irọlẹ o fi aiye silẹ nigbati o di ẹni adọrun ọdun.

(Wo yoku loju ewe kejọ)

## OLA NG'ORI OLA



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Alaiyeluwa Ọba Adeoji Aderẹmi, Ọni Ile Ifẹ ti o duro ti Iyafin rẹ lapa osi, on ni o tun gori oye Gomina, ipinlẹ Iwọ-orun, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ pelu Iyafin rẹ l'o duro ti wọn ti a nwo yi.

KABIYESI O! YOUR EXCELLENCY

# OLUKOTUN ati AJAGUNNA



Ni asiko ti Alaiyeluwa Sir, Adesoji Aderemi, Ọba jOni Ile-Ife gori oye Gomina ipinlẹ Iwọ-Orun ni a nwo aworan Dokita Nnamdi Asikiwe ti iṣe Akọnijẹ ile Igbimọ nla (Senate) ti o nki Oloye S. L. Akintọla ti Iṣe Olori Ijọba (Premier) ipinlẹ Iwọ-Orun ku oriire ti o je pe ijọba rẹ ni enia dudu kọ gba ipo Gomina nilẹ Nigeria.

OLUKỌTUN AT'AJAGUNNA,

OLOYE MEJI L'O MULE GBE RAWỌN.

## Olorun Pese Eran Igbe Lona Iyanu

ẸKAN, Ni ilu kan, ni agbegbe ilu Ekan awọn ara Ileto kan, da ọjọ ti awọn o nlọ ọdẹ, ọkunrin Aladura kan ti o nje Omọle sọ fun Balẹ Abule na wipe ki gbogbo awon ọdẹ Abule ti o nlọ ba wọn lọ si igbẹ ọdẹ na, ki o ki ibon rẹ ni ika merun merun, nitoripe ko si ọdẹ kan ti ko ni pa ẹran bọ wa ilẹ.

Ọpọ enia ko gbagbọ, nigbati ọjọ pe ni owurọ kutukutu ti awọn ti jade, nwọn de igbẹ de igbẹ titi agogo mẹrin irọlẹ la ko si ẹnikan ti o yinbọn de ipo ti awọn le pa ẹran Ọya.

Nwọn wa nro iru apara ti nwon o fi Ọmọle da nigbati nwon ba dele. Gbogbo awon ọdẹ na wa kori ilẹ. Bi nwon ti nlo bọni apata kan sidi lati ori oke kan, o si nyi bo wa ilẹ. Bi o ti nyi bo nilẹ, awon ọde na ri i. awon si ko ara duro.

Bi okuta na ti yi de ilẹ, o dun bi igbati nwon yin agba, erisirisi awon ẹranko lo si ba okuta na yi wa ilẹ.

Kini dun to yi, awon ọde na ko ibon ti won, nwọn pa wabiwosi ninu won, tobẹ ge ti ko fi si odẹ kan ti ko pa ẹran, eyiti o pa eran to kere ninu won lo pa eran Esuro.

Ẹru arawọrun ni awon ti o nwo oko ro lojo na, iṣe ni awon ọde nsjala dele, nigbati awon pin eran ti Bale tan, eto ni nwon pin ti Omole, ti awon to wa ko ara won lo si Oja-ogun.



Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri rà nibikibi, ko si wọn, o mó daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, iná-titàn ati lati mã fi yáná Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!


# Ore Meji Pin Ewon Odun Merin

IKẸJA Awon meji kan ti nwon jẹ ore ti nwon si tun jẹ arufin, ti oruko won nje Oseni Ayinde ati Antoan Joseph. Awon mejeji awonyi parapọ nwon lo ji moto Cycle (Scooter) ti okunrin ara Benin kan ti o nsise ni na ile egbogi Ijoba kan ti o mbẹ ni Oshodi.

Nigbati awon enia meji na ji kẹkẹ Alupupu na, nwon fe gbe lọ ilẹ Faranse, nigbati nwon de Agbamola nidi Iroko, ibẹ ni owo olopa ti tẹ won. Nwon si da won pada wa si kotu Ikeja.

Ọlopa ba awon enia na ṣe ẹjọ; adajọ si gba wipe awon odaran na jẹbi o ni ki nwon lo gbewa odun meji meji fun ẹnikọkan won.

# Itan Ajapa Ati Iroko

Ajapa wa bẹrẹ si ṣire pẹlu Ẹta wipe ki o mu abọ ode wa ki on jẹ ṣugbọn Ẹta ni ki o di ọla ọjọ rere Nigbati wọn da apara tan ti akoko to lati sun Ajapa ni ki Ẹta sun ni ita gbangba nitoripe ẹnikan nwa on bọ ni arọ ọla ki o ba le tete pe mi.

Ẹta ni ko buru o si gba bẹ o sun ni ita, nigbati o di dede agogo mẹwa alẹ ojo kan rọ ojo na si pọ pupọ tobẹ ti agbara ojo fi wọ Ẹta lo nibiti o sun si nigbati ilẹ mọ ti Iroko ji o gbe kumọ meji o gbe o di ile Ajapa, nigbati ode ohun o kan ilẹkun o ni Ajapa, Ajapa, Iroko ko gbọ ki ẹnikan dahun o tun pe Ajapa wa ji ṣugbọn ko le dahun nigbati o ka lara o ni Ẹta dahun dahun o wa nji ọrọ sọ ninu ile pe ki Ẹta dahun, Iroko wa gbọ ohun ninu ile ni o ba wọ ile ni o ri Ajapa nibiti o sa pamọ si o wa mbẹ Iroko ṣugbon ko gbọ ẹbẹ rara.

Ajapa wa ṣe ileri wipe on yio da gbogbo iṣu ti on ti gba lọwọ Iroko pada Iroko kọ jalẹ o si lu igba ẹhin Ajapa fọ yan-yan, bẹ ni o yẹ ki o ri fun Ajapa Oloju kokoro, Awọn Agbalagba ni nwọn npa lowe wipe "Ekinni kẹbẹ ekeji kẹbẹ ẹkẹta ajẹ-ijẹtan" bayi ni Ajapa ṣe fi oju kokoro pa ara rẹ.

Eyi ni opin itan na ẹ si tun ma gbọ omiran o.

## KI OLOWO TO KU AHUN TI KU ỌNA TI JIN

(Apa 2 Lati ọwọ Ẹṣọ)

Gẹrẹ ti Imologbe, Eriokiija ati aburo wọn kọ'a lọ tan ni Aje sọ wipe, aṣe irọ ni awọn ara-bi nwọnyi pa tobẹ. Elegbara bere pe kini o ri ti o fi sọ bẹ ? O dahun pe ọran igba ni nwọn di bi ọkọ ti nwọn si npọhun rere ẹkun.

Ọrunmila ko gba, Elegbara papaa jiyan Aje sọ fun wọn pe, ki o le dawọn lọju ki nwọn tele wọn lẹhin lo sile wọn lọwọ o.

Nigbati nwọn dele ti o pe die Ae sọ ara rẹ di iya arugbo o lo kanlẹkun, nwọn da lohun wipe iwọ tani ki li o fẹ? o si dahun pe on fẹ fan jna, nwọn ni ko pada sẹhin awọn nse nkan lọwọ.

Elegbara sọ ara rẹ di ọmọ kekere, o lọ o si fi ori silẹkun wole, ọmọ kekere, kan si adagbo ni nwọn fi pe, o si ri wipe ọran ni nwọn pa nitotọ.

Fun ohun ti nwọn ọmọde na ṣe yi, nwọn pin awọn mẹtẹta larin ara wọn. Aje yio pa ẹgbọn jẹ, Elegbara yio pa ekeji jẹ, Ọrunmila yio pa ọmọ kekere ina won jẹ.

(Koiti pari)

# Awon Olopa Meta Gb'owo Ehin

EKO. Awọn ọlọpa mẹta ni adajọ ṣa si ẹwọn lori ẹsun itopanpa gbo'wo ẹhin ni ọjọ Satide tokọja.

Awọn meji ti nwọn jẹ ọga ninu awọn ọlopa na ni adajọ ju s'ẹwon oṣu mejila mejila, okan yoku ti o jẹ ọmọ ehin jo si ewon oṣu mefa.

Ẹsun ti, ijoba fi sun ni wipe awon mẹtẹta parapọ gba owo pọun meji lowo okunrin kan l'ona eru ninu oṣu May odun yi.


HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas, Portable Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- money order for Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England

# ELETI - OFE

A-NJUWỌN KO ŞE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFE, LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XII. NO. 689. SATURDAY AUG. 20, — AUG. 26, 1960


# Egbe Afenifere Pegede

Ninu ibo ti a di ni ipinlẹ Iwọ-orun fi yan awọn ọjogbọn enia ninu Igbimọ Aşofin Ipinlẹ Iwọ-orun, ni ẹgbẹ Afenifẹre (Action Group) ti ijọba ipinlẹ na ti wa lọwọ wọn lati ọdun kejọ s'ẹhin tun pegede bori ninu ibo na, ti nwọn di bo ẹgbẹ Alakukọ (N. C. N. C.) mọlẹ pirapira. Eyi to ayọ, o si to ohun iduunu fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ati awọn alatilẹhin ẹgbẹ na nitoripe "Aja to lọ sile Ẹkun ti o pada bọ" bi a ba ri Aja na, ki a ki ku ewu. Awọn Alatako ẹgbẹ Afẹnifẹre ko gbe ọwọ kekere, otitọ l'o bori eke wọn.

Awọn enia ipinlẹ Iwọ-orun ni a şe ọpẹ fun lọpọlọpọ nitoripe "awọn ko fi oke ọlore b'aye" gẹgẹbi owe Yoruba. Nwọn mọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ọrẹ ati alajẹja wọn. Iwa imore ti awọn enia ipinlẹ Iwọ-orun fihan na l'o pa ẹgbẹ Alakukọ rẹ ninu Ibadan ti o ti jẹ ilu ti nwọn ti fẹsẹ rinlẹ şaju. Eyi nikan kọ, ni nibegbe ilu Ibinni, ti o tun dabi enipe ẹgbẹ Alakukọ fẹrẹ l'ẹsẹ nilẹ, jankolabọ ni awọn enia ibẹ şe ọrọ wọn. Eyi ko ha t'ayọ fun ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Ẹ da muso fun Oloye Awolọwọ, ẹ kan sara iyin si Oloye Akintọla. Ẹgbẹ Afẹnifẹre pegede, nwọn fi gbọrọ sebe.

## Apa Obinrin Kan Yo Mo Yandoka Lowo

ILORIN. Obinrin kan lọna Alapa, ti a gbọ wipe awon Ọlọpa mu ọkọ rẹ nitoripe o gbe iyawo ẹlomiran. Obinrin na sọ fun Alikali wipe, ọkunrin na ko gba on rara, on funra on li on wa fẹ ati wipe, Ijoye ilu ni ọkọ ti on ti nfẹ tẹlẹ ri, ti on ti wa fẹ egbe yi, ninrinla, o ni ki ki na ti fi ọkowo silẹ wa fẹ agbe.

Şugbon awon Yandoka ati awon Dongari ko gba fun obinrin na lati sọ ohun kan mọ, nwọn ni ayi fi ki o pada si ile ọkọ rẹ Ijoye ilu ti o ti nfẹ tẹlẹ. Bi ko ba si pada sile ọkọ atijọ, nigbana awon na ju ọkọ titun na si ẹwọn, awon yio ri bi yio pada tabi ko ni pada.

Ijoye ọkọ rẹ atijọ na mbẹ ti obinrin na fi nsọ wipe, bi on ba sọ ladi abajo ọrọ ti on fi Jade, o daju pe gbogbo enia ni yio wa lehin on, ati wipe bi awon ko ba jẹki on sọ ti inu on jade, ti nwọn ba ju ọmi ọkọni ati alaiṣe yi sile ẹwọn on yio şe gudugudu meje.

Awon Yandoka dahun wipe; Kini nwaju teni o nşe iru ileri bẹ? Alikali sọ wipe obinrin na soro odi si ijoba, ki won lo fi agbẹ na si inu ile, o di ọsẹ meji ki on to tun soro rẹ.

Awon Dongari ti Agbẹ na mole. Obinrin na si dide, o fonja pooti. Bi Alikali ti dide lati ma lo sile, o sare mọ, o fi ori jin latiya, o si dako, Alikali si fi idi sile.

Nitori ti awon Yandoka gbe Alikali dide ti nwon si ki nwon fa obinrin na, foti ni apa rẹ yo mọ wọn lọwọ, o di pe ntuka.

Gbogbo awon ara Alapa nsare wa wo ran obinrin na, Alikali wa pe Ijoye na wipe ki o jẹki obinrin na fẹ eniti o wun. Ni nwon ba fi agbe sile. Agbe to si lo gbe obinrin na dide ti o si fi apa re sibiti o gbe ti jade. Ẹrin ni awon mejeji rin dele.

## OLOPA KAN LU JIBITI, O WO EWON

Olopa Ilorin kan, ti o mo iwe ti o si şe bi eyiti o gba ni a gbọ wipe o lu obinrin kan ni jibiti nipa gbigba owo lọwọ rẹ lati ba şe nkan, o si lo owo na fun anfani ara tirẹ.

Bi ẹjọ na ti lọ niyi: Ọlọpa ti o njẹ Bawa Yaro, jẹbẹti lati ba obinrin kan fa ẹjọ obinrin na si ko owo le lọwọ eyi Rishi ko mu wa a lọ owo ni a ri a ko ri abọ.

Iye owo ti o gba lọwọ obinrin na jẹ 25s oruko obinrin na njẹ Amilẹgbe, bọẹ owo ba wọlẹ si, adajọ ni kio lo si ẹwon ọdun kan.

# Awon Opomulero Ijoba Iwo—Orun



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye S. L. Akintola, eniti nwọn dibo fun nibi Ogbomoso, on ni Olori Ijọba Ipinlẹ Iwo-orun ilẹ Nigeria.



Ẹniti a nwo yi ni Oloye E. A. A. Fadahunsi eniti nwọn dibo fun ni agbegbe Ilẹ Egbado, o si gba ipo Minister, Olutọju Ijọba.



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye A. O. Adeyi, ti işe ọkan ninu awọn Minister Ipinlẹ Iwọ-orun ilẹ Nigeria.



Ẹniti a nwo yi ni Ogbeni J. E. Otuyo, ẹniti nwọn ti o wọle nibi idibo tiwọn koja lọ yi ni agbegbe Mid-west, o si gba ipo Minister fun ilu rẹ-




# Adamodi Dokita W'ewon

Ọpọlọpọ awon ti nwon ba ti kọ ẹkọ diẹ nipa iṣe egbogi pipo tabi ti nwon ti ri oye diẹ nipa Pharmacy, Druggist ati Chemistry ti nwon ko si duro kọ ẹkọ na dara-dara tabi ki nwon kọ ẹkọ na de opin, iru awon enia bayi ni a ma egbọ wipe nwon o ra aberẹ ti awon Dokita fi ngun ni aberẹ ati egbogi rẹ, nwon o lọ si ọna arọko nwon o lọ si ọna arọko nwon o si bẹrẹ si gun awon alaimokan ni aberẹ.

Ọpolọpo einu iru awon enia bawonyi ni awon ọlọpa ti ramu ni agbegbe ilu Enugu. Bi nwon gun won ni abere yi tan, nwon o si gba owo girimoyan lọwọ won.

Nipa ṣiṣe bayi ọpọ awon enia lo ti gba ibẹ di oku ọrun, iru rẹ ni ti ọkunrin Oniṣegun palanta kan ti awon npe ni Andrew Ogbe ti ko kọṣẹ iṣegun ti o nlọ gun won ni abẹre nilu Oturpo ilu kan labẹ ijoba Ila-orun.

Ko lero wipe ọwọ ọlọpa le tẹ on nibiti o gbe ngun aberẹ yi fun won ti awon enia to fẹ gun ṣeru bo, ko fura titi oyinbo Ajẹlẹ fi rin de ọdọ rẹ.

Ajẹlẹ bere lowo rẹ wipe kini orukọ Dokita tirẹ? O dahun pe Dokita Andrew ni.

Ajẹlẹ—Tani fun ọ laṣẹ lati ma gun abẹrẹ nibi?

Andrew— Nṣe ni mo fi ara mi jin lati ṣe bẹ.

Ajẹlẹ—Nibo ni iwọ ti kọṣẹ yi?

Andrew—Ni Pharmacy College ni Yaba ni.

Ajẹlẹ—Iwe ẹri rẹ da?

Ọrọ wa di womi awo ọ.

Ajẹlẹ ti o mu na lo ṣe idalẹ lori re wipe ni ko ba ri lati ṣe o san ... fi iba ... ti o ni lọwọ ṣe iṣe agbẹ lu ... mi lu jibiti kakiri lọ. Ko ni ... lati mu aberẹ ... dani ati gru awon egbogi buruku ti ... ka mọ lọwọ, nitorina ki o lọ si ẹwọn oṣu mẹfa.

NO. 91

## Fifi Oruko Sile Fun Awon Omode Ti Yio Bere Ile Iwe L'odun Ti Mbo 1961

Alamojuto eto iṣẹ ẹkọ fun Ijọba Apapọ Naijiria, Ọlọla Aja Nwachuku, ti fun ọeiti ndele de ọga ile iṣẹ Ijọba ti nṣe eto l'ori ẹkọ, Ọgbẹni E. J. Moses, ni aṣẹ lati bẹrẹ si gba oruko awọn ọmọde ti yio ṣẹṣẹ bẹrẹ ile iwe l'Eko l'ọdun ti mbọ silẹ, gẹgẹ bi ofin Ijọba ti wọn ṣe ni ọdun 1957.

2. Nwọn yio bẹrẹ si gba orukọ silẹ lati agogo mẹjọ si agogo mẹwa l'aro ati agogo mẹjọ si mẹfa ni aṣalẹ lati ọjọ kejidelogun oṣu kẹjọ (August) ọdun yi titi di ọjọ kọkandelogun oṣu (August). Ọna mẹtadinlogoria na ati awọn ile iwe ti Ijọba lọwọ si yio jade ninu ikede ti Ijọba yio ṣe ninu iwe irohin nigbati o ba ku ọsẹ kan ki awọn bẹrẹ si fi orukọ awọn ọmọ wẹwẹ na silẹ.

3. L'ọjọ ti a wi wọnyi, ki olukuluku obi mu ọmọ rẹ ti o ba bi ni ọdun 1955 pẹlu iwe ọjọ ibi rẹ lọ si ibi ti awọn ba ti gba orukọ silẹ fun ile iwe ti o fẹ ki ọmọ na lọ.

4. Ko ni si aye fun ọmọkọmọ ti ko ba fi orukọ silẹ ni asiko ti a wi yi lati bẹrẹ ile iwe ni ibẹrẹ ọdun ti mbọ, 1961: afi bi o ba jẹ pe awọn obi rẹ le fi han gbangba pe Eko ni nwọn ngbe ni ibere ọdun 1960, ṣugbọn awọn ko si si Eko mọ l'asiko ti awọn afi orukọ silẹ.

## Oloye Awolowo Gbayi Nilu Eko



Irohin ko to afọjuba lojo kọdogun osu August, 1960, nigba Oloye Awolowo wọ ilu Eko pẹlu iyi ati ẹyẹ, tobẹgẹ ti o fi jẹ wipe kukiri ighoro ati kọro ilu Eko ni gbogbo enia fi uke wipe "Awol Awoli Awoli".

## Awon Faranse Fe Dan Orungbe Wo

ALGIERS—Awọn Faranse mẹwa kan dide lati ilu Algiers lati lọ pago ri arin meji okun yanrin, ki nwọn si gbe ibẹ fun osu mẹfa wo lati fi dan okun yanrin na wo, nitori o jẹ wipe fun iwọn egberun bawọ ko si omi, ko si igbo, igi tabi koriko ti o jẹ pe yanrin, yanrin, ogodogede yanrin ti o mu enia de koko ẹsẹ lo jọ bẹ ṣua, boya ibẹ yio ṣe gbe fun enia ati eranko.

Eyiti o kereju ni ọjọ ori awọn enia mẹwa ti o nlọ na ni omo ọdun marundinlogoji nwọn si ti mura awọn ohun elo dani nitori idagiri ona.

Ohun ti nwọn fẹ se ni pe bi oru inu okun yanrin na yio ba jẹ eyiti enia yio le fi ara da pẹlu orungbẹ ibẹ. Nigbati nwọn ba de ọhun, nwọn ko ni gbe agọ kanna papọ, ṣugbọn nwọn o pin ara wọn si meji meji ninu agọ kọkan, gbogbo awọn mẹwẹwa ti o nlọ yi jẹ ọjọgbọn, ti nwọn si ti kọ ẹkọ pari ninu ile ẹkọ University.

(Wo yoku loju ewe keje)

## Enito Fi Ibinu Ya Ilu Wewon

IDOMA. Ọkunrin kan ti nwọn npe ni Agbaji lo ri awọn ẹnikan ti o njo, o fi ibinu wọ agbo ijo na lọ o si fi ọbẹ ọlọjẹ meji ya ilu Gbẹdu ti nwọn nlu. Ibẹ ni ọlọpa ti ra Agbaji mu ti nwọn si fa lọ siwaju adajọ kotu nla.

Esun ti nwọn fi sun okunrin na ni pe ni akoko ti Foye kan ti o njẹ Oṣonu Oriwe ti iṣe odajo agba nilu kotu Agala fi njo ilu Gbẹdu, ti gbogbo enia si bẹrẹ si yọ, nipa biba ijo ilu Gbẹdu na, ibẹ ni okunrin Agbaji yi ti fi ibinu wọ agbo ijo na, o si tẹ ọbẹ ṣigoro bọ ilu na, ọsi ya kaalẹ.

Adajo to da ejọ rẹ bere wipe ngbo; Agbaji, kini o ri so si oro yi? O si dahun pe, irọtẹ ni ou ya ilu na. Idi re ti on fi ya ilu na ni wipe ilu Gbẹdu jẹ ilu Awo; eyiti Oloye Oṣonu Oriwe ko ni ẹtọ si lati jo nitori ko si ninu awọn ẹgbẹ Awo ti o ni lati jo ilu na. Adajọ ba wi fun lori ẹsun yi wipe, o ba alafia awọn enia jẹ nitori awon gbe nyo nitorina ki o lo si ẹwọn oṣu mẹfa. Ni Agbaji ba dide ti o gboora gba a.

## Aboru Aboye Ati Abose Apa 2

Lati ọwọ Eso

Nigbati Orunmila kan awọn ọmọ Olofin mẹta yi, 'Aboru, Aboye Abose o duro ti wọn o mba wọn sọrọ ṣugbọn nwọn ko fẹ sọrọ gere o bere si wa ọrọ lẹnu wọn ṣugbọn nwọn ko dara ya ọkan ninu wipe jọwọ fi mọ sile o jare ebi lo mpa mi lati owurọ wa nitoripe oko jẹ ohun kan ki nto kuro nile aṣọ mi si pọ ti ngo fọ ebi wa npa mi.

Orunmila dahun wipe howu ! eyiol kosoro o sọ apo Ifa rẹ kalẹ o fun ẹni kọkan ni akasu ẹkọ kọkan ati itan adiẹ kọkan

Nigbati awọn wundia mẹta nwọnyi jẹun ti nwọn yo, ara wọn ya nwọn si bere ibiti Orunmila nlọ, o dahun pe Ọlọfin lo ranṣẹ pe on pe ki on yara wa fi oju kan on.

Awọn ọmọge mẹta na rohin fun ọrunmila nipa ẹran abami mẹta ti awọn ọde Ọlofin pa Nwọn si tun rohin fun Ọrunmila nipa gbogbo awon Awo Ifẹ ti Ọlọfin ti mo yara oke ala Nwon si tun so fun wipe ki orunmila mase gbagbe lati ki Ifa se oko won.

Nibiti ni Ọrunmila ba wọle rọ Olofin lo Ọlofin so fun pe ki o wa ye ifa wo fun on o bere lowo rẹ wipe Ifa kini Ọba da loni, Ọba si dahun pe Egotan meji.

(Koiti Pari)

## ELETI — OFE DA'RABA

**Kere o!**

A ti ni orişirişi egbogi fun arun Inarun ati arun Jẹdijẹdi, (Bitter Tonic Liquid of Life) Tete wa ra tirẹ, t'ọkunrin ati t'obinrin ki o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORE
7, Egerton Road, Lagos.

# Electricity Corporation Of Nigeria

## INVITATION TO TENDER

### CONSTRUCTION OF DWELLING HOUSES AT AFAM

The Electricity Corporation of Nigeria invites Tenders from Contractors registered in category 'E' and above of the Federal Government Works' List of Contractors or in equivalent categories of the Eastern, Western and Northern Regional Governments Works' Lists of Contractors for the construction of 3 NO. Bungalows, 1 NO. Guest Chalet and 9 NO. Junior Service Quarters at Afam.

The Tender Form, Conditions of Contract and Bills of Quantities will be forwarded to Contractors who fall within the categories stated above and whose applications together with a deposit of £5 – which will be refunded on receipt of a bona fide Tender - are received at the office of the Secretary Electricity Corporation of Nigeria, Electricity Headquarters, 13 Broad Street, Private Mail Bag 2030, Lagos, not later than 26th August, 1960.

The closing date for receipt of Tenders will be 15th September, 1960.

The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the lowest or any Tender.

Further information concerning this Contract may be obtained on application to the Civil & Hydro Electric Development Engineer at this Headquaters.

**George W. Nicol**
ACTING SECRETARY TO THE CORPORATION

## Egbe Awon Osise Kowe Ebe si Olotu Ijoba

EKO.– Ọgbẹni H. P. Adebola kowe rẹ̀ ase si Ọlola Prime Minister, Alhaji Sir, Abu Bakar Tafawa Balewa wipe, ki o maje ka ohun ti awon egbe Trade Union Congress wa se lelpe yi si, nipase owo ọfẹ fun aloyọ Ominira Ilẹ Nigeria. Ki o ma si se je ki iwa ti awon ba lọjọ na bi on nise.

Ọgbẹni Adebola sọ wipe ninu osu June 3rd 1960, on kowe kan si Oloye Okotie-Eboh nipa ọhun owo ọfẹ yi, sugbon o sọ fun won pe on ylo fi iwe ti mo bọ rẹ̀ si Minister of Pension fun esi tirẹ.

Nitorina, a bẹ ọ ki o ba wa ti sure si ki awon si le fun wa ni owo osu kan. Ao se ipade Whitely Council lọjọ Friday 9th Sept., 1960, nibẹ ni ao ti se ifẹnuko lori owo osu kan.

### OLOYE AKINTOLA ṢE IKILO FUN IGBIMỌ IBILẸ ILESHA

IBADAN Irohin to si wa leti wipe, awon Igbimo Ijoba Ibilẹ Ilesha sọ fun Oba Ilesha wipe ki o fi ori oye Oba silẹ. Pantiwa ?

Awọn Igbimọ na sọ wipe idi rẹ ti awon fi sọ wipe ki Oba Ilesha fi ori oye silẹ nipe o fẹ da igbimọ Ilesha si meji, o si tun sọ Afin rẹ di ile ẹgbẹ ti awọn eniyan fi ri aye lati ma lọ bura ninu rẹ.

Lori ọro yi ni Premier Ipinlẹ Iwọ-oorun na so le lori, wipe Ijoba on ko ni gba igbakugba fun Ijoba ibilẹ kan lati ma sọ isọkuso si awon Oba lara tabi awon Ijoye.

Igbimọ Ijoba ibilẹ Ilesha ti pinnu lati le Ọba Owa Ilesha Alaiyeluwa Ogunmokun Biladu Keta jade kuro lori oye rẹ. o sọ pe, on fẹ ki o ye gbogbo enia wipe Igbimọ Ilesha ko ni ẹtọ bẹni nwọn ko ni asẹ lati yọ Oba ilu kuro ni oye.

Olotu Ijoba so wipe asoju ni Ijoba Ibilẹ jẹ fun Ijoba Ipinlẹ rẹ, nitorina awọn ko ni asẹ ti o ti tayọ asẹ ti Ijoba Ipinlẹ ba pa, eyi ko jẹki nwon ni asẹ lati yọ Oba.

## Olotu Ijoba Nlo Be Ilu Saro Wo



Irohin ta si wa leti wipe Ọlọla Sir Abu Bakar Tafawa Balewa Olotu Ijoba Apapọ nlọ se abẹwo si Ilu Saro fun ọjọ meji pere lati lo je Ipe Ijoba Ilu na.

O dabọ o, Sule ajumo.

### AWON EGBẸ ZUMURATUL HUJAJI FẸ KỌ ILE ẸKỌ GIGA

EKO Irohin ta si wa leti wipe awọn awujọ Alhaji (Zumuratul Hujjaji) se ipade nla kan ninu ile Dr. Alhaji Salawu ni ita Fokolajọ nilu Eko, ohun ti awọn si se ipade na fun ni wipe, awon ro o ni ẹtọ wipe o yẹ ki nwọn kọ ile ẹkọ giga kan nibiti nwọn o ti ma kọni ni ilọsiwaju ẹko ninu ede Yoruba, Gẹsi ati Larubawa.

Lẹhin ti nwọn se apero won na tan nwon se iyiro iye owo ti nwọn ni ninu awujọ won nigbati Lẹhin ipero ni DR. Salawu ti ise Alaga awọn ijọ Alhaji fi oriṣiriṣi ohun aladun se ipanu fun won. Lẹhin ti nwọn fi ikan panu tan, ni ipade tuka.

## NI IRANTI

BABA WA OWON



ALHAJI ABDUL KARIMU COLE

Ẹniti o fi aiye silẹ ni Ogunjọ osu August, 1959 (20th August, 1959.)

Alabi Opo ni mọja nikan
Alabi Okin ọmọ Ọlofa
Ọmọ Onisaro Ọwọnga,
Ọmọ Onibu Ẹja.
Saro o gbe agba eiyawo,
Atun arugbo se l'ẹge.
Bada Alhaji Eko,
Orun rere o.
Aduke ati Fari.

## Eniti O R'aiye Ti Ko Sa, Ara Iku L'o Nya

Enyin ololufe wa, dakun fi eti si mi ... mase ba won ... wipe "Nko bere enia, ... Oloriun". Nigbati ... ko ... enia ... iyawo ni ... yio ... lero Olorun ti a ko ... Awon enia ... ti ekie ti lo ... wipe awon ko bere enia.

Iono ... isze enikeji, enia Sango ... wole, wala! ... Oba keso ... Aja ... ode ... lo so nia ni Ende-Lnu. ... nje be aiye ... lo, fun u. Iwo ko mo wipe enia ... re Arokundajo ti o ... Agbon, enia lo ... di ogbun, ogbun ki ... Fosa.

Lodun 1901 ni itan ti mo fe so yi sele. Eniti ... wa ni Eko ... awon ope ni Oredegbe. Giwa ati Akorin egbe ... Nwon jijo nigun awon ... kanna ni awon ... giriyawo. Ki lo dan to yi.

Danmole Olorin Eko ri to ki ... Oro ko dun ... ri ... kirin yi ni ojude Sanni ni Eko gbogbo awon enia ti o wa nibi aburo ojo na ... kan ana ti nwon ... ri ... Gbo bi Danmole ti korin ni ale ojo na.

B'o raiye ko se f'aiye o (2ce)
B'o ba r'awo lesan
Ogboti ko mo,
Oro winiwini l'o po
lowo won
Ojupa!

B'ere ba dere ojupa
Won a pe iya aja ko
lese
B'o r'aiye ko se f'aiye

Tabi ... na ni o jare, itan ti a ... pe Iyawo Giwa ... jumo lo nlo ki Iyawo Akorin. Semesamo nigbagbogbo ti o ba de ile Akorin ... pelu Akorin a ma ba ara won mu faaji lori ...

Olorun ... si Iyawo Akorin, ara re ko gba gbogbo ... ti ... re ... pelu Iyawo Giwa. Nigbati ara re ko gba ... lo ... iwosan re ... o di odo Giwa o ... jowo odo ... ni mo wa ... fun iyawo ... ki ... so ... ni ... ko si ojo kan ti ... ni ... fun a.

(Keku pari)

## TOKO—TAYA KU LOJO KANNA

(O bere loju ewe kini)

Bi a ti nse ... fun ti isinku Oloye ... gbuke ni a tun gbo ti iku yawo Oloye ... ni oruko re nje Iyafin Alice Olomide ni ... ojo keji ti oko re ku ojo Thursday 11th osu August 1960 obinrin na de ... ajo re nile aiye nigbati o di eni odun ... ni doruu.

A se ... fun awon mejeji ... Afrika ni idi Ape ... ti a je da ... oruko awon omo re niwonyi:-

Iyafin Victoria Fowotade Coker ... Eko Iyafin Comfort ... Ogbeni James Osanlawon Daniel Oluyegun ati ogunlogo awon omo omo.

Ehin baba ati iya adara o.

## ORO TI KO MO-YAN LORI



Ogbeni Tennyson Makiwane ti ise okan ninu awon asiwaju awon Oselu ni ipinle apa isale Guusu Afrika so wipe, gbogbo awon asiwaju lo tigiri nipa

Gbolohun oro kan ti ... leun Dokita E.A Esin ... ni ... kan ninu ... Asofin ile Nigeria ti o lo ... Gusu ile Afrika ... wipe ile Nigeria ... South Afrika ... Eyi je oro ti ko ba ... Nigeria ...

## OFIN IBANI L'ORUKO JE

Gbogbo awon derena moto lo mo gedegbe wipe, bi awon ba wa moto won ni iwakuwa, awon o lugbadi awon olopa. Bakanna ni, bi enia ba wa ninu ile re, ti o si gba oju ferese ju ohun kan nu si ode, ti nkan na si sesi lo ba eni kan, ti o nkoja lo, ti o si palara, eni na bi o ba fe le pe onile na lejo ki o si gba iye owo ti o ba wu lowo re.

Enia le se gegebi o ba ti wu la'ye, sugbon oluwere ko gbodo fi ominira tire pa enikeji lara. Apara dida, ewo ... tabi iwa jagidijagan lodi si ofin.

Bi enikan ba dipara adajo, o le se si ofin ki enia ma fi enia dapara nipa ohun ti eni na ko se tabi ki o ko ... iwe eyi ni ofin npe ni ... donrun ese ti oluware ko se mo.

Niti wipe ki a wule bu enia ni gbu, eyi ko je ohun kan. Tabi ki a wipe olori ile ni okunrin yi tabi ki a pe ni opuro, awon Oselu ko nka eyi si nkan gunmo. Sugbon ki a so fun Loya kan wipe, ope enia ni, eyi buru lati gbo be pitor'pe awon Loya ni a gbagbo wipe awon ni ogbon ... Ko si eniti yio gbo ti nwon pe Loya kan ni omugo ti ko ni ... si oro na.

Bi mo ba so fun Ojo Ijogbon wipe o'e ni o, Ponun marun lo yo ninu apo mi lana, Ojo Ijogbon ko ni le pemi lejo ki o si yege; nigbati o ba pe kotti si eniti o gbo nipa oro na, ko si s'eniti o mo nipa ohun ti a nso.

Sugbon bi mo ba so oro na nipoju eniketa nigbana ni mo to ba Ojo Ijogbon ni oruko je. Bi Ojo Ijogbon ko ba tile si nibe ti mo fi so fun ore mi kan wipe, o je mo po, Ojo Ijogbon ji mi ni poonu marun lana. Yala Ojo wa nibe tabi ko si bi o ba fe, o le pe mi le'o pe mo ba oun ni oruko je.

Bi mo ba so fun iyawo mi pe Ojo Ijogbon ji mi ni Ponun marun, lehin na ti oro na wa di mimo fun Ojo Ijogbon Ojo ko le pe mi lejo ki o yege, nitori'pe iyawo mi ni mo ba soro, eni ati iyawo mi si je okan niwaju ofin.

## Omode Ko Nje Obi Beni Agba Ko Nje Oye

(Lati owo Joseph Afolayan)

Nigba atijo Baba kan ati omokunrin kan je ore ara won nwon a si jijo ma ba ara won lo si ode. Nwon jijo lo si ode papo lojo kan, nwon jeun yo tan Baba na wa n'e obi lowo beni omodekunrin ore re ni ki o fun on ni obi je. Baba na si fesi dahun wipe omode ki i je obi.

Omode kunrin na dake, ko si binu. Somo-somo omoba ni omokunrin na, Nigbati o se oba ilu na salaisi, Nwon sin'u oba o gbe mose, nwon wa nwa eni yio ropo nwon mu omokunrin ore baba yi ni nwon yan lati fi joye oba ilu na.

Nigbati omokunrin yi wa lori ipo oba, gbogbo enia lo ngbadun re ninu ipo ola oba re Lehin odun meta, Ijoye ilu kan salaisi Awon ara ilu nwa eniti nwon o fi ropo ijoye ti o ku na.

Nwon so fun Baba ti o so pe omode ki lobi, wipe on ni yio bo si ipo ijoye ti o ku na awon ni lati mu lo fi han oba ilu pe eniti nwon fe fi joye na niyi.

Gere ti oba fi oju kan a, ni eba ti mo o, o si ranti oro re ijosi wipe omode ko n'je obi. Oba so fun awon enia ti o fe fi Ijoye na je oye wipe, Ha? omode ko n'e obi be na ni agba ko nje oye. Beni oba ko lati fi okunrin na joye.

Bayi ni oba na ko ti ko ... okunrin na je oye eyi na ni ohun ti o di owe ... di oni wipe „Bi omode ko ba nje obi bena ni agba ko nje oye."

Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street, P. O. Box 457 Lagos Phone 23370